# Jesu Kristi



# Jesu Kristi



Wycliffe

Illustrations et texte de Willem de Vink

Propriété littéraire © 1993 Stichting Wereldtaal, Houten, Pays-Bas
Edité en néerlandais sous le titre 'Jezus Messias'
Traduction en yoruba © 2008 UEEB (Union des Eglises Evangéliques du Bénin)

Tous droits de traduction, de reproduction et d'adaptation réservés pour tous pays

Imprimé aux Pays-Bas
Co-édition mondiale organisée par Wycliffe Pays-Bas, B.P. 150, 3970 AD Driebergen, Pays-Bas




Ɛ gbɔ́ o ! kilodé ti ɔ̀kpɔ̀ eniyàn wɔnyi fi kpéjɔ leti odò ?


Ɛ murasilɛ̀ !
Ijɔba Ɔlɔrun fɛ́rɛ̀ dé !



Ɛ yikpada !
Nitoriti a ti fi ààké le orí ishan igi náà lati gé e lulɛ̀.
Mo wi fun yin : Gbogbo igi ti kò bá so èso rere ni a o gé lulɛ̀, ti a o si sɔ sinu iná.
Bi o ba ri bɛ́ɛ̀, kinni a nilati she ? Talo le gbe igbe aiye mimɔ́ ?
Otitɔ́ ni. Kosi ɛniti o le bɔ́ kuro lɔwɔ ìdájɔ́ Ɔlɔrun. Shugbɔn lɛ́hin mi ni ɛniti yóo fi Ɛmi Mimɔ́ tɛ̀ yin bɔmi mbɔ̀wá.
Ɛ bɛ̀rɛ̀ si gbe igbe-aiye titun. Ɛ gbà kpe kòsi ire kan ninu yin. Ɛ she ìtɛ̀bɔmi lati fihàn kpé ɛ ti ronukpìwadà.
Eleyi ni yoo jɛ́ àmì kpé ɛ fɛ́ gbe igbe-aiye titun.


Johannu onitὲbɔmi ni oniwàásu náà ti nsɔrɔ yi leti odò.
Ɛniti mbɔ lέhin mi yi lagbara ju mi lɔ. Yoo fi Ɛmi mimɔ́ ati iná Ɔlɔrun tὲ yin bɔmi, yoo si fun yin li ayikpada ti o jinlὲ. Jesu li orukɔ rὲ.
Oun niyi...
Emi ni o yɛ ki iwɔ tὲ bɔmi.
Bέὲkɔ́ ! Sáà tὲ mi bɔmi ki ìfέ Ɔlɔrun ba le jɛ shishe.
Eyiyi li ayanfέ ɔmɔ mi, inu mi dun sii kpukpɔ̀.
Nigbanáà li ohun kan dún lati ɔrun wa...
Eyiyi li ayanfέ ɔmɔ mi, inu mi dun sii kpukpɔ̀.


O ti nlɔ bii ɛgbèrun meji ɔdun ti Johannu onitébɔmi ti nmura dide Messáyà náà. Ni akoko naa, ilɛ̀ Israeli jɛ́ akpakan lara ijɔba Romu ti ó kere.
KAPANAUMU
GALILI
NASRƐTI
KANA
ISRAELI
JORDANI
JERUSALƐMU
JUDEE
Aláilágbára orilɛ̀ ede Ju ti a nkpɔ́n loju nreti dide Messáyà ti a ti sɔ asɔtɛ́lɛ̀ rɛ̀ nikpasɛ̀ awɔn woli. Oun ni yoo mu ododo Ɔlɔrun bori.
Johannu onitɛ̀bɔmi wá nfi Jesu hàn leti Jɔ́ɔ́dani.
Wòo ! Eyiyi ni ɔdɔ̀-agutan Ɔlɔrun tó ko ɛ̀shɛ̀ aiye lɔ.
Lɛ́hin itɛ̀bɔmi rɛ̀, Ɛmi Ɔlɔrun dari Jesu lɔ si ijù.
Fun ogoji ɔ̀san ati ogoji oru, Jesu kò jɛ ohunkohun. Bi o ti ngbadura, o wá ri ishipaya ishɛ́ rɛ̀ kedere.
Ki o bá le ri ìmushɛ, oun nilati fihan wikpe èto Ɔlɔrun lo jɛ́ lati mu ki awɔn eniyan bɔ́ kuro lɔwɔ agbára iku.
Bɛ́ɛ̀ni, Babá ! ifɛ́ rɛ ni mo fɛ́ she.
Oun nilati gbogunti Satani, alade àiri ibi òkunkun, ti ntikpasɛ̀ iku ati ikparun jɔba ninu aiye.


Sibɛ̀, ɔ̀ta ndán Jesu wò ki o ba le mú u shinà ninu ishɛ́-iránshɛ́ rɛ̀.
*Bí ɔmɔ Ɔlɔrun ni ɔ nitootɔ́, sɔ awɔn okuta wɔnyi di àkàrà.*
Bɛ́ɛ̀kɔ́ ! nitori o wà ni akɔsilɛ̀ kpe : Ko jɛ́ ounjɛ nikan ni o le mu ki eniyan wà láàye bikoshe gbogbo ɔ̀rɔ̀ ti Ɔlɔrun ba ti sɔ.
*Bi ɔmɔ Ɔlɔrun ni ɔ, fo lati ori ile Ɔlɔrun yi. A kò ha ti kɔ̀we rɛ̀ kpe awɔn angɛ́li yo fi ɔwɔ́ wɔn gba ɔ mu bi ?*
Bɛ́ɛ̀kɔ́ ! a ti kɔ ɔ́ kpɛ̀lu kpe : iwɔ kò gbɔdɔ̀ fijà lɔ Oluwa Ɔlɔrun rɛ.
*Nitorináà, wò ó ... ! wolɛ̀, foribalɛ̀ fun mi, emi o si fi gbogbo agbára ile aiye fun ɔ.*
Kuro nibi Satani !
nitori a ti kɔ ɔ́ kpe : iwɔ yoo ma jubà oluwa Ɔlɔrun rɛ, oun nikan ni iwɔ yoo ma sìn.
Nigbanà ni satani fii silɛ̀ fun sáà kan, awɔn angɛ́li ɔrun sɔ̀kalɛ̀ wá lati ma she iránshɛ́ fun un.
Lɛ́hin eyi, Jesu wá kún fun Ɛmi Ɔlɔrun nigbati o nkpadà lɔ si Galili. O jɛ́ àgbegbe ìhà àriwa, nibiti awɔn eniyan kpɔ̀ gidi. Nibɛ̀ gan-an ni oun gbe dàgbà. Loju ɔ̀nà, awɔn eniyan darakpɔ̀ mɔ́ ɔn. Nwɔn fɛ́ mɔ̀ bi oun ni Messáya náà ti awɔn woli ti sɔ asɔtɛ́lɛ̀ rɛ.


Igbéyàwó kan mbɛ ni Kánà ninu awɔn kpɛ̀tɛ́lɛ̀ Galili...
Jesu si wà nibɛ̀ kpɛ̀lu ìyá rɛ̀ ati awɔn ɔ̀rɛ́ méèlokan.


Shugbɔ́n bi ayɛyɛ naà ti nlɔ lɔ́wɔ́...
Irú ishòro wo leyi ! Ɔti ti kparí.
Ohun ti Jesu bá ti wi fún yin ni ki ɛ she.
Ɛ kpɔn omi kún inú awɔn ìkòkò wɔnyi, ki ɛ si jɛ́ ki olorí ayɛyɛ náà tɔ́ ɔ wò.
?
Omi ni bi ? Kinla ! ɔti ni ! Irú ɔti wo leyi !
Kilóde ti iwɔ fi gbé ɔti rere yi kpamɔ́ titi di isisiyi ?
Eleyi ha she le rí bɛ́ɛ̀ ? Ki a sɔ omi di ɔti ? Kinla ! Taló le she e ?
Ishɛ́ ɔwɔ́ Jesu ará Nasarɛ́tì ni !
Tanni oun jɛ́ nigbanaà ?


Jesu wá bɛ̀rɛ̀ ishɛ́-iránshɛ́ rɛ̀ ni Galili nibiti o gbé nsɔ̀rɔ̀ ijɔba Ɔlɔrun nigbangba fun awɔn eniyàn ni ilú kékere awɔn akpɛja kan ti nwɔn nkpè ni Kapanáúmù.
Nibɛ̀ gan-an li ó gbé yan awɔn ɔmɔ-ɛ̀hin rɛ̀ àkɔ́kɔ́.
Peteru ! jɛ́ a wɔnu ibú lɔ : iwɔ yóo sɔ awɔ̀n rɛ sinú rɛ̀.
Olukɔ́ni, gbogbo òru yi li a fi shishɛ́, sibɛ̀ a kò rí ohunkohun mú.
Shugbɔ́n nitori ɔ̀rɔ̀ rɛ...
Kinla ! ohun iyalɛ́nu wo leyi !


Ɛ ma bɔ̀ ! Jakɔbu ! Johannu ! Ɛ ma bɔ̀ ! Eyiyi li o kpɔ̀ jùlɔ ninu ɛja ti a ti nmú li ɔjɔ́ aiye wa.
Lɔ kúrò lɔdɔ mi, Oluwa. Ɛléshɛ̀ ni emi.
Máà bɛrù, Peteru. Lati akókò yi lɔ, akpɛja eniyan ni iwɔ yóo máa she.
Ɛ ma bɔ̀, ki ɛ si máa tɔ̀ mi léhin ! Emi o sɔ yin di akpɛja eniyàn.
Ɛ máa tɛ̀lé mi !


Jesu nbá irin-àjò rɛ̀ lɔ si gbogbo agbègbè Galili kpɛ̀lú awɔn ɔmɔ-ɛ̀hin rɛ̀. Ó nkede ijɔba Ɔlɔrun. Ó nmú awɔn aláisàn larale, o nlé awɔn ɛ̀mi èshù jáàde kúro lára awɔn eniyàn. Kpɛ̀lu iyalɛ́nu ni awɔn eniyàn fi ntɔ̀ ó lɛ́hin. Nwɔn kúro nibigbogbo wá, ni awɔn igbèriko miràn ati ni Jerusalɛ́mu, ti o jɛ́ olú-ìlú ilɛ̀ Israeli kpɛ̀lú...
Ɛni ayɔ̀ ni awɔn aláiní nitori tiwɔn ni ijɔba Ɔlɔrun.
Ɛni ayɔ̀ ni awɔn ti ebi nkpa ati ti oungbɛ ngbɛ sikpa òdodo nitoriti nwɔn o yó.
Ɛni ayɔ̀ ni awɔn ɛniti nsɔkún nitori Ɔlɔrun yóò tù wɔn ninú.
Ɛni ayɔ̀ ni yin nigbati nwɔn bá nkɛ́gàn yin nitori mi. Ɛ má yɔ̀, ki ɛ fò sókè fún ayɔ̀, nitori èrè nlá li ó dúró dè yin li ɔrun.


Ɛ máa she si awɔn ɛni iyókù gɛ́gɛ́bi ɛ ti fɛ́ ki nwɔn she si yin.
Ɛ fɛ́ràn awɔn ɔ̀tá yin, ki ɛ si máa gbàdurà fun wɔn.
Nikɔ̀kɔ̀ ni ki ɛ ma shore funni, kìí si she ni gbangba.
Ɛ kiyèsara yin ! Nitori ɛniti o bá shojukòkòrò si obirin kan lati bá a lòpɔ̀ ti she panshágà tan li ɔkàn rɛ̀.
Ojú dabi imɔ́lɛ̀ fun ara ni. Bi ojú bá riran kedere, gbogbo ara rɛ ni yóo ma gbádùn imɔ́lɛ̀. Shugbɔ́n ti oju rɛ bá nshàisàn, gbogbo ara rɛ ni yoo máa gbé ninu okùnkùn nigbànáà.
Ɛ kò le sin ɔ̀gá meji lɛ́ɛ̀kannáà. Ɛ yàn Ɔlɔrun tabi owó.
Ɛ mashe àniyàn niti ɔjɔ́ ɔ̀la. Ɛ kɔ́ wá òdodo Ɔlɔrun ná, eyiti ó kù li a o si fikún un fun yin.
Ɛ she ohun ti mo bá wi fun yin. Kikɔ́ ni a o kɔ́ igbé-aiye yin lori àkpata nigbànáà, kò ni jɛ lori erùpɛ̀.



Li ɔjɔ́ kan, awɔn eniyàn dúró li ayiká ilé kan nibiti Jesu gbé wà ni ilú Kapánáumù.
A ò le rekɔja rara lááárin ɔ̀kpɔ̀ eniyàn wɔnyi !
Bi a bá òrùlé sɔkalɛ̀ lɔ nkɔ ?
Kilo wá shɛlɛ̀ ?
Ɛ fi wɔn silɛ̀. Awɔn ɔ̀rɛ́ wɔnyi ní igbàgbɔ́ nlá.
A dári awɔn ɛ̀shɛ̀ rɛ jì ɔ.
Kinla ! She o gbɔ́ nkan tó nwi ?
Ó nsɔ̀rɔ̀-odì.
Ɔlɔrun nikanshsho ni ó le dári awɔn ɛ̀shɛ̀ jini.
Njɛ́ ó rɔrun ki a wikpé "a dári awɔn ɛ̀shɛ̀ rɛ jì ɔ̀" ni tabi "dide" !
Mo wi fun yin kpé: Messáyà ni agbára lati dári awɔn ɛ̀shɛ̀ jini, o si le wikpé : Dide, gbé ibùsùn rɛ, ki o si má rin !


Ohun iyalɛ́nu wo niyi !
Wò ó ! Mo le rin... Mo nrin !
O nrìn !
Sibɛ̀, kò jɛ́ gbogbo eniyan ni ishɛ́ Jesu dùnmɔ́, kpàtàki jùlɔ awɔn olorí ɛ̀sin ti nwɔn nshɔ́ ɔ lati wò bi oun bá nkpa òfin mɔ́. Njɛ́, ofin kɔ̀ lati shishɛ́ li ɔjɔ́ isinmi.
Ɔkunrin kan niyi ti ó rɔ́ lɔ́wɔ́. Njɛ́ ó tɔ́ ki a máa shore tabi ki a máa she buburu li ɔjɔ́ isinmi.
Na ɔwɔ́ rɛ.
Mo rí iwòsàn !
Kpikpa li o yɛ ki a kpa á.
Ɛ jɛ́ ki a bu awɔn olorí ɛ̀sin ti ngbé ni Jerusalɛ́mu gbɔ́ wikpé ó ntan awɔn eniyan jɛ́ ni.


Aféfé lile kan dide... Jesu bá yà si akpákan kpɛ̀lu awɔn ɔmɔ-ɛhin rɛ̀ ninu ɔkɔ̀ oju omi kan lori adágun Galili.
Gbà wá Oluwa ! a nrì wɔnú omi lɔ !
Kilóde ti ɛ fi nshojo bɛ́ɛ̀ ? Igbàgbɔ́ yin dà ?


Ɛ Dákɛ́ !
Ɛ Kpɛnumɔ́ !!!
Nwɔn ba gúnlɛ̀ leti òkun kan nibiti idákɛ́rɔ́rɔ́ gbé wà. O si she lojijì...
RÀÀÀÀ !
15


Ɛnikan ti o li ɛ̀ru bá yɔ si wɔn !
Jesu mbɔ̀wá !
Yéè ! Hà...
Njɛ... Jesu, iwɔ ni !
Ɛmi èshù, jade kurò lára ɔkunrin yi !
Kinni o kpa wá kpɔ̀, Jesu ɔmɔ Ɔlɔrun ɔ̀gá- ogo julɔ ?
Kinni orukɔ rɛ ?
Legioni ni, nitoriti a kpɔ̀.
Jɛ́ ki a wɔnu awɔn ɛlɛ́dɛ̀ wɔnyi lɔ.
O ti yá !


?
Kinla, kinla... Mo ri iwòsàn !
Ɛ lɔ ! Ɛ lɔ kúrò nibiyi !
Mo fɛ́ bá yin lɔ.
Kpadà lɔ si ile rɛ, ki o si ròhin gbogbo ohun ti Ɔlɔrun she fun ɔ.


Ɛ gbɔ́ ! mo wá lori ilɛ̀ aiye lati she ifɛ́ Baba ti o rán mi nishɛ́ ni. Emi kò dá ohunkohun kan she fun ara mi.
Nigbà kpukpɔ̀ ni Jesu ma nlɔ sibi ìkɔ̀kɔ̀ lati lɔ gbadúra.
Bɛ́ɛ̀ ni o wá yan awɔn ɔmɔ-ɛhin rɛ̀ mejilá lɛ́hin ti o ti fi òru gbadura tán. O wá ran wɔn lɔ káàkiri ni méji-méji ni ilɛ̀ náà. O wá fún wɔn li ashɛ lori awɔn agbára okùnkùn ati lóri awɔn àisàn.
Peteru ati Anderu jɛ́ tɛ̀gbɔ́n-tabúrò...
Gɛ́gɛ́bi Jakɔ́bù ati Johannu.
Bakannáà ni a rí Filippi ati Natanaɛli...


Tomasi ati Matteu (agbowode atijɔ́ ti nshishɛ́ fun awɔn ará Romu).
Taddeu ati Jakɔ́bù miran.
Nikɛhin simoni ti o njɛ́ Seloti ati Judási Iskariotù.
Ɛ lɔ ! Ɛniti o bá gbà yin, oun ni ó gbà mi. Ɛniti o bá si gbà mi gba ɛniti ó rán mi nishɛ́.
Awɔn ɔmɔ-ɛ̀hin mejilá fi ayɔ̀ kpada ti ibi ishɛ́-iránshɛ́ wɔn dé. Jesu fɛ́ lɔ sibi ikɔ̀kɔ̀ kan kpɛ̀lu wɔn, shugbɔ́n ɔ̀kpɔ̀ eniyan wá ndi i lɔ́wɔ́.
Ikórè kpɔ̀, awɔn alagbàshe ni kò tó nkan. Ɛ bɛ Oluwa ikórè lati rán awɔn alagbà she lɔ kó ikorè lɔ si ilé.


Biotilὲjέ wikpe ilὲ ti nshú nlɔ, Jesu tun nkɔ́ni lέὲkɔ́, o si tun nwonisàn sibὲ...
Filippi, nibo ni a le gbé rí búrέdì rà ti yóo tó lati fi bɔ́ gbogbo eniyan wɔnyi ?
Igba owó fàdákà kò tilὲ lè tó !
Ɔdɔmɔdekunrin kan mbɛ nibiyi ti o ní búrέdì máàrun ati ɛja meji lɔ́wɔ́. O tán.
Ɛ jέ ki awɔn eniyan jóòko ni ɛgbɛgbέ adɔ́ɔ̀ta adɔ́ɔ̀ta.
Jesu wá dúkpέ lɔwɔ́ Ɔlɔrun...
O wá nkpin awɔn burέdi ati awɔn ɛja náà, gbogbo wɔn si jɛ ounjɛ li ajɛyó.


Ɔnà bayi ni Jesu gbà fi bó ɛgbɛgbɛ̀run eniyan.
Oun ni Messáyà náà ti o nilati wá.
Ɛ jɛ ki a fi adé de Ɔba !
Ɛ wò ó ! àjɛkù agbòn mejilá ni a rí kójɔ.
Ɛ jɛ ki a ran awɔn eniyan náà lɔ si ile wɔn, ki ɛ si rekɔjá lɔ li ɛ̀gbɛ́ keji kpɛ̀lu ɔkɔ̀ oju omi. Niti emi, mo tun mbɛ lori òke nibiyi lati gbadura.


Nikɛhin...
AAA !
Iwin kan !!!
Ɛ máa bɛ̀ru,
emi ni !
Oluwa, bi iwɔ ni
nitòotɔ́, kpashɛ ki
ima bɔ̀ lɔdɔ rɛ.
Máa
bɔ̀.
Oluwa,
gbà mi !
Peteru, èéshe ti
o fi shiyemeji ?


Ɔkpɔ̀ eniyan li o fɛ́ fi adé de Jesu ɔba. Nwɔn nreti kpe nikpashishe bɛ́ɛ̀, oun yóo lé awɔn olugbé Romu jade. Awɔn miran ngàn an siwáju ati siwáju sii. Nwɔn kà á si ɛnikan ti o lewu fun ilú , nwɔn si nwá lati gbe awɔn eniyan dide sii ki nwɔn bá le kpa a.
Olukɔ́ni, nigbàwo ni iwɔ ti wà nibiyi ?
She nitori burɛ́di ti mo fún yin ni ɛ fi nwá mi ni ?
Ɛ mashe shàniyàn nitori ounjɛ ti nbàjɛ́, shugbɔ́n ɛ kúkú ma wá eyiti o wà titi láe.
Emi ni burɛ́di ti nfunni ni ìye titi láe. Ara mi ni mo fi lelɛ̀ ki araiye bá le nì ìye.
Bawo ? She ɔkunrin yi yóo fi ara rè funni lati jɛ ni bi ?
Ó nsɔ̀rɔ̀ òmùgɔ̀.
Ɛ jɛ́ ki a lɔ !
Ó ntan ɔ̀kpɔ̀ eniyàn jɛ ni. Ɛ wá !
Ɛ kò fɛ́ lɔ bi awɔn ɛni iyókù bi ?
Lɔdɔ tanni awa o lɔ ? Iwɔ, Oluwa, iwɔ ni o ní awɔn ɔ̀rɔ̀ iyè ainikpɛ̀kun.


Jesu kò shalái bá àtakò kpade siwáju ati siwáju sii. O wá kuro ni agbègbè ilú Galili. O nbá ishɛ́ rɛ̀ lɔ ni awɔn àgbègbè Israeli. Awɔn ɔkunrin ati obirin ti nwɔn jɛ́ ɛgbɛ́ awɔn ɔmɔ-ɛ̀hin si bá a lɔ.
Galili
Israeli
Jerusalɛmu
Kò kpɛ́ ti o fi mú ɔ̀nà Jerusalɛ́mu tɔ̀.
Lóju ɔ̀nà...
Tanni awɔn eniyàn nfi mi kpè ?
Awɔn kan sɔ kpé wòli ni ɔ.
Ɛnyin náà nkɔ́ !
Tanni ɛ rò kpé mo jɛ́ ?
Iwɔ ni Kristi, ɔmɔ Ɔlɔrun alààyè.
Ɛ mashe wi nkan fun ɛnikɛni. Mèssáyà nilati lɔ si Jerusalɛmu, ki oun bá le jiyà, ki oun si kú nibɛ̀. Shugbɔ́n li ɔjɔ́ kɛta, yóo jínde.


Léhin odi Jerusalému ni nwɔn gbé kan awɔn arúfin náà mɔ́ agbelebu.
O jé ohun iyà nla kan ti awɔn ara Romu ma nlò.
Ɛnikéni ti o bá fɛ́ tɛ̀le mi nilati gbàgbe tabi sɛ́ ara ountikararɛ̀, ki oun si ma gbé àgbelèbú rɛ̀.
Ɛniti ti o bá fɛ́ lati gba ɛmi ara rɛ̀ là yóo kpàdánù rɛ̀ ni, shugbɔ́n ɛniti o bá kpàdánu rɛ̀ nitori mi, oun ni yóo rí i.
Ki ɛ mɔ̀ wikpe Ɔlɔrun kanshosho ni mbɛ.
Ati kpe ohun ti o she kpàtàki julɔ ni ki ɛ fi gbogbo agbára yin féràn Oluwa Ɔlɔrun yin, ki ɛ si féràn ɛnikeji yin gégébi ɛ ti féràn ara yin.


Aisàn kan ti o burú ni ɛ̀tɛ̀ jɛ́. Nigbà aiye Jesu, awɔn alaisàn ɛ̀tɛ̀ ma ngbé inu awɔn abúle ti o jinnà sibiti awɔn alára didá sháshá gbe wà.
Nigbati awɔn adɛ́tɛ̀ ba nkɔja lɔ, nwɔn nilati jɛ́ ki awɔn ɛni iyókù mɔ̀ kpɛ̀lu ohun igbe.
Alaimɔ́ ! Alaimɔ́ !
Jesu ! Olukɔ́ni ! Shàánú fun wa.


Ɛ lɔ fara yin hàn awɔn àlùfáà.
Lɔdɔ̀ àlufáà... She ki ó yɛ̀ wa wò ?
Njɛ́ awa iba rí iwòsàn bi ?
?
!
Bɛ́ɛ̀ni ! a rí iwosàn.
Ara wa le !
Ɛ wá !
Alleluyà ! Ɔlɔrun dára ! A dúkpɛ́ !
Gbogbo ɛnyin mɛwá kɔ́ ni a wòsàn ? Awɔn mɛsán iyókù dà ? Ko ha tɔ́ ki awɔn náà dukpɛ́ lɔ́wɔ́ Ɔlɔ́run bi ?
Dide ! Igbàgbɔ́ rɛ kò mu ɔ laradá nikan, o gbà ɔ là kpɛ̀lu.


Awɔn olori Ju ti ngbé ni Jerusalɛmu rán awɔn eniyan lɔ lati lɔ she iwáàdi lori Jesu. Nwɔn  kò dɔ́gba rárá kpɛ̀lu gbogbo ohun ti o nshe kpatakpata nì.
Nitori Jesu a máa lɔ sɔ́dɔ̀ awɔn eniyàn buburu, awɔn ashɛ́wó ati awɔn agbowó-orí, ti ma nbá awɔn ará Romu kɛ́gbɛ́kpɔ̀.
Messáyà dé lati wá awɔn ti nwɔn sɔnù kiri ati lati gbà wɔn là.
Jesu máa nmu awɔn alaisàn láradá li ɔjɔ́ isinmi kpɛ̀lu.
Rí iwòsàn !
O máa nfi ifɛ́ tɛ́wɔ́gba awɔn ɔmɔde.
Ɛ jɛ́ ki awɔn ɔmɔde wá sɔ́dɔ̀ mi, nitori ijɔba Ɔlɔrun jɛ́ ti awɔn ɛniti o dabi wɔn.


Nwɔn ránshɛ́ kpe Jesu ni Betani, ilu kekere kan ti mbɛ leti Jerusalɛmu. Lasaru nshàisàn. Awɔn ɔ̀rɛ́ Jesu ni oun ati awɔn arabirin rɛ̀, Marta ati Maria, jɛ́. Shugbɔ́n nikɛhin, nigbati Jesu wá dé Lasaru ti kú, o si ti tó bi ɔ́jɔ́ mɛ́rin ti nwɔn ti sin in...
Oluwa !
Oluwa, ibá jɛ́ kpe o wà nibiyi ni, arakunrin mi kì bá ti kú.
Marta ! Arakunrin rɛ yóò jinde.
Bɛ́ɛ̀ni, mo mɔ̀ bɛ́ɛ̀. Yóo jinde ni àjinde òkú lɔ́jɔ́ ikɛhin.
Emi ni àjinde ati iyè. Ɛniti o bá gbà mi gbɔ́ yóo yè. Njɛ́ o gba eyi gbɔ́, Marta ?
Bɛ́ɛ̀ni, Oluwa, mo gbàgbɔ́ ! Iwɔ ni Kristi ɔmɔ Ɔlɔrun náà ti o nilati wá sinu aiye.
Nibo ni ɛ tɛ́ ɛ si ?
Oluwa, wá wò ó !


Jesu bá bù sɔ́kun. O fɛ́ràn rɛ̀ kpukpɔ̀.
Njɛ́ kò le she e ki Lasaru ma ku bi ?
Ni ilɛ̀ Israeli, nwɔn a máa fi òróro ikunra kun awɔn òkú lara, nwɔn a si wá tɛ́ wɔn sinu sààre kan ti nwɔn gbɛ́ ninu òkuta.
Ɛ yi okuta náà kurò lɛ́nu sààre.
Oluwa, ó ti nrùn, nitori o ti tó ɔjɔ́ mɛ́rin ti o ti wà nibɛ̀.
Ɛ o ri ògo Ɔlɔrun.
Baba, mo she eyi ki nwɔn lè gbàgbɔ́ kpe iwɔ ni o ran mi nishɛ́.
LÀÁÁSÁRÙ ! JADE WÁ !
Ɛ tú ashɔ kuro lara rɛ̀, ki ɛ si jɛ́ ki o máa lɔ.


Ɔkan awɔn olori ɛ̀sin ko wá balɛ̀ mɔ́ nitori òkiki Jesu to nkàn.
Ɔkunrin yi ti wá nshe ishɛ́ iyanu kpukpɔ̀.
Awɔn ara Romu yóò she nkan ti a kò bá mú u.
Nwɔn yóò wó ilé ɛ̀sin wa, nwɔn yóò si run orilɛ̀-edè wa.
Ɛ jɛ́ ki a lɔ ! O sàn ki ɔkunrin kan kú jù kpe ki gbogbo orilɛ̀-edè kú lɔ.
Jesu yi nilati kú ni.
Lati igbà náà lɔ, awɔn olori Ju nwá ɔnà ti nwɔn ibá fi fà Jesu le awɔn ara Romu lɔwɔ́. Awɔn nikan ni o lé dá ɛ̀bi ikú fun eniyàn.


Nigbànáà, ɔdun kan wá nlɔ lɔwɔ́ ni Betani.
Maria !
Shugbɔn... owó nlá ni láfindà yi jɛ́.
A ba sáà tà a ki a si fi owo rɛ̀ fún awɔn tálákà !
Fi i silɛ̀ Judasi ! O kpa láfindà yi mɔ́ di ɔjɔ́ ti a o tɛ́ mi sinu iboji ni !


Ajɔ̀dún irekɔjá sunmɔ́le, ɔ̀kpɔ̀ eniyan wá nlɔ si Jerusalɛ́mu.


Nigbati awɔn olori ɛ̀sin ngbèrò lati mú u, Jesu wá ntɛ̀siwaju ninu irin-àjò rɛ̀ lɔ sihà ilú-nlá.


Nigbati Jesu dé, ɔ̀kpɔ̀ eniyàn wá nhó ìhó ayɔ̀ sii...
Hòó yéèè !
Hòó yéèè !
Ki ɛniti mbɔ̀wá li orukɔ Ɔlɔrun ki ó kpɛ́ !
Ògo ni fun ɔba Israeli !
Gbogbo eniyàn wá nsare lɔ sɔ́dɔ̀ rè.
Bi nkan ti she ri gbà yi kò le gbè wa.


Ile ɛ̀sin nlá Jerusalɛ́mu jɛ́ ikpò isin awɔn Ju.
Nigbà àjɔ̀dún irekɔ́já, nwɔn a máa fi awɔn àgùtàn rúbɔ.
Akpakàn ninu irúbɔ ni nwɔn ma nrú ninu ilé Ɔlɔrun fun imúkuro ɛ̀shɛ̀ niwáju Ɔlɔrun.
Sibɛ̀ irubɔ wo ni o le gba awɔn eniyàn là kurò ninu awɔn ɛ̀shɛ̀ wɔn nitòótɔ́ ?
Ninu àgbàla ile Ɔlɔrun náà ni awɔn eniyàn ntà, nwɔn nshe kpàshí-kpàrɔ̀ owó : òwò wɔn nlɔ déedée.
Lojiji, Jesu bá wɔlé...


Ilé Ɔlɔrun gbɔdɔ jɛ́ ile àdurà ni. Ɛ ti wá sɔ ɔ di ìle awɔn olè.
Ɔkunrin yi léwu. Sibɛ̀ gbogbo eniyàn ni ngbɔ́ tirɛ̀ !
O yɛ ki a wá ɔnà kan ti a o gbà fi kpa a biotiwukiori.


Ɛ jɛ́ ki a fi ɛ̀tàn mú u, ki a si kpa á.
Shugbɔ́n kò nilati jɛ́ nigbà àjɔ̀dún. A kò nilati dá ìrukèrúdò kankan silɛ̀.
Bi mo bá fà Jesu le yin lɔ́wɔ́, èló ni ɛ o fún mi ?
Judasi, ɔ̀kan ninu awɔn ɔmɔ-ɛ̀hin rɛ̀ ni !
Emi yóò fà Jesu lé yin lɔ́wɔ́ !
A o fún ɔ ni ɔgbɔ̀n owó fàdákà, iye owó ɛrú kan.


Ni ikɛhin ɔjɔ, ki àjɔ̀dún irékɔjá tó dé, Jesu wá nbá ɔ̀kpɔ̀ eniyàn ti o kpéjɔ ninu ilé ɛ̀sin sɔ̀rɔ̀ biotilɛ̀jɛ́ wikpe awɔn olori ɛ̀sin ntakò ó.
Jesu wá bérè lɛ́nu Peteru ati Johannu kpé ki nwɔn kpèsè ɔdɔ́-àgùtàn àjɔ irékɔjá silɛ̀.
Ni alɛ́, Jesu ati awɔn ɔmɔ-ɛ̀hin mejilá bá kpéjɔ ni ilú fun àsè ìrékɔjá.
Ɛmi o she nkan ni alɛ́ yi !


Ɔkan mi fɛ́ gidigidi lati ba yin jɛ ounjɛ àjɔ̀dún irékɔjá yi ki ntó jìyà.
Awɔn olori orilɛ̀-èdè a ma jɔba lori awɔn ti ngbé lábɛ́ àshɛ wɔn.
Shugbɔ́n bi ɛnikan bá fɛ́ jɛ́ ɛni nlá láàrin yin, jɛ́ ki o ma she iránshɛ́ yin.
Emi wà lááárin yin bi ɛniti nshe iránshɛ́ ni .


Oluwa, iwɔ kò ni wɛ ɛsɛ̀ mi bi ɛrú , ki a má ri !
Bi emi kò bá wɛ̀ ɛ́sɛ̀ rɛ, a jɛ́ pé iwɔ kò le wà kpɛ̀lu mi ni, Peteru.
Bi o bá ri bɛ́ɛ̀, Oluwa, mo mbɛ̀ ɔ, wɛ orí ati awɔn ɔwɔ́ mi kpɛ̀lú.
Kòsi ohun tó kù fun ɛniti o bá ti wɛ̀ mɔ́ ju kpé ki o wɛ ɛsɛ̀ rɛ̀ lɔ.
Ɛ nkpè mi ni olukɔ́ni ati Oluwa, ɛjɔ́ yin tɔ́. Njɛ́ bi mo bá nwɛ ɛsɛ̀ yin, àkpɛrɛ kan ni mo fi lelɛ̀ fun yin bayi. Ɛ ma tɛ̀lé e.
Ɔkan ninu yin ni yòò fi mi hàn fun ɔ̀tá.
Emi ni bi ?
Rárá !
Judasi, ohun ti o ní i she, tètè she e !


Ɛ tɛ̀siwájú ni shishe eyi
ni iránti mi...
Ɛ gbà !
Eyiyi ni ara mi.
Ɛ mu ago yi ! Eyi ni ɛ̀jɛ̀ mi
ti a o ta silɛ̀ fun yin.
Eyi ni majɛmu titun ti
Ɔlɔrun bá yin dá.
Wòó ! òfin titun ni mo fi fun
yin kpé ki ɛ fɛ́ràn ara yin
gɛ́gɛ́bi mo ti fɛ́ràn yin.
Bi ɛ bá fɛ́ràn ara yin, nigbànáà
ni gbogbo eniyàn yóò wá mɔ̀
kpé ɔmɔ-ɛ̀hin mi ni ɛ jɛ́.
Oluwa, emi o ma tɛ̀le ɔ lɔ
nibikibi. Emi o tilɛ̀ yɔ̀nda
aiye mi fun ɔ.
Peteru, ki àkùkɔ tó kɔ,
iwɔ yóò sɛ́ mi lɛ́ɛ̀méta.



Jesu kpɛ̀lu awɔn ɔmɔ-ɛ̀hin mɔkànlá ti nbá a lɔ bá jáde kúrò láàárin ilú li òru. Judási kòsi láàárin wɔn.
Emi o fi yin silɛ̀ lɔ, shugbɔ́n Baba yóò rán ɛ̀mi òtitɔ́ si yin ti yóò ràn yin lɔ́wɔ́, yóò si ma bá yin gbé nigbàgbogbo.
Ɛ kúkú ti mɔ ɔ̀nà ibi ti mo nlɔ.
Emi ni ɔ̀nà, òtitɔ́ ati ìyè. Kòsi ɛniti o lè dé ɔ̀dɔ̀ Bàbá bikòshe nikpasɛ̀ mi.
Ɛ dúró nibiyi. Emi nlɔ gbadúrà niwaju diɛ̀.
Bàbá, bi ó bá shéeshe, ki ìyà yi rekɔja lori mi.
Shugbɔ́n ìfɛ́ rɛ ni ki o jɛ́ shishe, kìí si she temi.



Ɛnyin kò lè bá mi shɔ́nà fun wákàti kan ? Ɛ dide, ki ɛ ma wòó ! Ɛniti yóò fi mi lé ɔ̀tá lɔ́wɔ́ sunmɔ́tòsi.
Ɛniti mo bá ti fi ɛnu kò li ɛnu ni ɛni náà. Ɛ mú u !
Ɛ kú alɛ́, olukɔ́ni.
Judási, iwɔ fi ɛnu ko Messáyà lɛ́nu lati fi í lé ɔ̀tá lɔ́wɔ́ ?
Oluwa, she ki a jà ni ?
Rárá ! Ɛ ma she ohunkóhun !
Nwɔn bá mú Jesu, nwɔn si fà á lɔ. Gbogbo awɔn ɔmɔ-ɛ̀hin bá fi í silɛ̀, nwɔn si sá.


Nwɔn bá fa Jesu lɔ niwajú Olórí Alùfáà, ti o jɛ́ ɔ̀gá awɔn Júù. Peteru ati Johannu wá ntɛ̀lé wɔn lókèrè.
Peteru bá wɔnu àgbàlá lɔ.
Sɔ fun wa, iwɔ náà ko ha wà kpɛ̀lú rɛ̀ bi ?
Bawo ! Emi kò tilɛ̀ mɔ̀ ɔ !
Ɔkan ninu wɔn ni o jɛ́ sibɛ̀.
Rárá o !
Ará galili ni ɔ, ɔkan ninu wɔn ni o jɛ́.
Rárá o, mo búra.


Kòkòró kooo !
Lókèrè...
Rò ó wò diɛ̀ ki o sɔ tanni ɛniti ó lù ɔ ?
Li òwúrɔ̀, a fa Jesu lɔ siwaju ilé- ɛjɔ́ awɔn Júù.
Ɔmɔ Ɔlɔrun ni ɔ bi ?
Iwɔ ti fi ɛnu ara rɛ sɔ ɔ.
Ó sɔ̀rɔ̀-òdì ! Ikú ni ó tɔ́ sii ! Ɛ jɛ ki a fà lɔ siwájú ilé ɛjɔ́ ilú Rómù.


Nwɔn bá fa Jesu lɔ siwaju Pilátù, ti o jɛ́ baálɛ̀ Rómù.
Awɔn olóri Júù wá ndá a lɛ́ɛ̀bi, nwɔn si nru awɔn eniyan sókè sii.
Iwɔ kò gbɔ́ gbogbo ɛ̀sùn ti nwɔn fi nkàn ɔ ? Sɔ̀rɔ̀ !
Kinni iwɔ she gan-an ?
Mo wá lati shɛlɛ́ri òtitɔ́ ni.
Kinni òtitɔ́ wá jɛ́ nigbànáà ?
Emi kò rí ɛ̀bi kankan lara rɛ̀. Nigbà àjɔ írékɔjá, o jɛ́ àshà wa lati dá ɛlɛ́wɔ̀n kan silɛ̀. Ɛ yàn Bárábà tabi ɔba awɔn Júù.



Bárábà !
Bárábà !
Kinni ki emi she sí i wayi ?
Kàn an mɔ́ àgbélèbú !
Ɔba li ó shebi oun jɛ́.
Ɔba li ó nfi ara rɛ̀ kpè. Bi iwɔ bá dá a silɛ̀, iwɔ kò jɛ́ ɔrɛ́ Késárì nigbànáà.
A dá ɔ silɛ̀ ! Iwɔ ni nwɔn yàn dikpò Jesu.
Bárábà ti a dálɛbi ìkpàniyàn ni a dá silɛ̀.
.. 37, 38, 39 !
Emi kò lɔ́wɔ́ ninu ikú ɔkunrin olóòótɔ́ yi.
A kí ɔ ! Ɔba awɔn Júù !


Ɔkunrin ɔ̀hún niyi.
Kàn an mɔ́ àgbélèbu !
Kàn an mɔ́ ɔ !
Kàn an mɔ́ àgbélèbu !
Pilátù wá fɔwɔ́siwé idalɛ̀bi ikú. Jesu wá ru igi àgbélèbú rɛ̀ lati fi rin lori awɔn ɔ̀nà Jerusalɛmu.
Nibiti nwɔn gbé kpa á lɛ́hin odi ìlú ni nwɔn nkpè ni Gɔ́lgɔ́tà (eyiti ó túmɔ̀si "Ibi agbári").
Nibɛ̀ ni awɔn ɔmɔ-ogun gbé kan Jesu mɔ́ àgbélèbú.


Judási wá káàbámɔ̀.
Mo dɛ́shɛ̀.
Mo fi aláilɛ́shɛ̀ lɔ́rùn hàn fun kpikpa.
Kiló kàn wá ! ɛjɔ́ rɛ ni !
A kan Jesu mɔ́ àgbélèbú li agbedemeji awɔn arúfin meji kan.
Baba, dáríjì wɔn nitori nwɔn kò mɔ ohun ti nwɔn nshe.



Pilátù wá fi akɔlé kan kɔ́ si orí àgbélèbú. Edè mɛ́ɛ̀ta ni nwɔn fi kɔ ɔ́ wikpé: "Jesu ɔba awɔn Júù".
IESVS NAZARENVS REX IVDAEORVM
Jesu kɔ̀ lati mu ɔtí kan ti a she lati fi mú ara rɔ̀.
Awɔn ɔmɔ-ogun bá dìbò lé ashɔ rɛ̀ lori.
Bi ɔmɔ Ɔlɔrun ni ɔ, sɔ̀kalɛ̀ kúrò lóri àgbélèbú !
Shebi o gba awɔn ɛlomiràn là !
Gba ara rɛ, ki o si gba awa náà là !
Iwɔ kò bɛ̀rù Ɔlɔrun ? Ni tiwa, a njɛ iyà ti o tɔ́ si wa ni, shugbɔ́n ni ti oun kò she ohun kan ti ó burú.
Ránti mi nigbàti iwɔ bá dé inu ijɔba rɛ.
Lóòótɔ́ ni mo wi fún ɔ, loni yi ni iwɔ yóò kpɛ̀lu mi ni ɔrun rere.


Nigbàti ó tó nkan bi agogo mejilá ɔsán, òkùnkùn shú bolὲ.
Maria, iyá Jesu ati Johannu, ɔkan ninu awɔn ɔmɔ-ὲhin rὲ bá dúro lέbá àgbélèbú.
Iyá ati ɔmɔ ni ɛ jέ nisisiyi.
Ɔlɔrun mi, Ɔlɔrun mi, èéshe ti iwɔ fi kò mi silὲ ?
Orùngbɛ ngbɛ mi.
Baba, li ɔwɔ́ rɛ ni mo fi ὲmi mi lé.
Ohun gbogbo kpari !


Jesu wá kú ni nkan bíi agogo mɛta ɔ̀sán. Awɔn ɔmɔ-ogun kan bá fi ɔ̀kɔ̀ gún un li ɛ̀gbɛ́, omi ati ɛ̀jɛ̀ bá tú jáde.
Ó wà ni akɔsilɛ̀ ninu Bibeli wikpé : "A fà a lɔ bi àgùtàn si ilé alákpatà."
"A shá a lɔ́gbɛ́, a si kpa á lára nitori awɔn ɛ̀shɛ̀ wa." Shugbɔ́n ó ti kú nisisiyi.
Njɛ́ oun ni Messáyà náà ti ó nilati wá bi ?
Ɛ jɛ́ ki a lɔ tɔrɔ òkú rɛ̀ lati sin in.
Josɛ́fù ará Arimatia ati Nikodémù bá gbé òkú Jesu lɔ. Nwɔn fi òróró olóòrùn didùn she itɔ́ju ara rɛ̀, nwɔn wá fi ashɔ-ɔ̀gbɔ̀ titun wé e, lɛ́hinnáà ni nwɔn wá tɛ́ okú rɛ̀ sinu iboji Josɛ́fù ti nwɔn fi òkuta nlá kan dí lɛnu.


Lɛ́hin ɔjɔ́ isinmi, awɔn obirin méèlókan tó nkáànu bá lɔ si ibojì.
A ti yi òkúta kúrò lɛ́nu iboji !
Eéshe ti ɛ fi nwá alàáyè láàárin awɔn òkú ? Ó ti jí dide. Ɛ lɔ ròhin fun awɔn ɔmɔ-ɛ̀hin.
Nigbàti awɔn obirin náà wá kpadà lɔ, Peteru ati Johannu bá yára lɔ si ibojì.
Kinni... Kiló wá shɛ́lɛ̀ gan-an ?
Kosi nkan nibɛ̀... Ó shòfo kpátákpátá ni !


Maria bá lɔ si etí ìbojì.
Obirin, tanni iwɔ nwá, kilódé ti iwɔ si fi nsɔkún ?
Oluwa mi ni nwɔn ti gbé lɔ. Bi iwɔ ni o gbé e lɔ ni, sɔ ibiti o gbé tɛ́ ɛ si fun mi ?
Maria !
Olùkɔ́ni !
Mashe dá mi dúró. Sɔ fun awɔn arákunrin mi kpé mo nkpadà lɔ sódɔ̀ Baba mi ti ó jɛ́ baba yin, sódɔ̀ Ɔlɔrun mi ti ó jɛ́ Ɔlɔrun yin kpɛ̀lú.



Li ɔjɔ́ kannáà, meji ninu awɔn ɔmɔ-ɛ̀hin wá nfi ibànújɛ́ ɔkàn ròhìn nikpa ohun gbogbo ti o shɛlɛ̀ kpɛ̀lú arinnà-àjò kan ti ó darakpɔ̀mɔ́ wɔn.
Ɛ kò ha gba awɔn ɔ̀rɔ̀ asɔtélɛ̀ gbɔ́ bi ? Kò ha wà ni àkɔsilɛ̀ wikpé Messáyà nilati jiyà, ki o tó bɔ́ sinu ogo rɛ̀ bi ? Gbogbo eleyi ti wà ni àkɔsilɛ̀ lati ɔjɔ́ kpikpɛ́ wá.
Bi nwɔn ti njɛun lɔ́wɔ́, àlejò wɔn bá nù mɔ́ wɔn lójú lojiji...
Jesu ni.
Lɛ́sɛ̀kɛsɛ̀ ni nwɔn kpadà lɔ si Jerusalɛ́mu lɔ bá awɔn ɔmɔ-ɛ̀hin iyókù.
Maria ati Peterù kpɛ̀lú.
Awa rí Oluwa !
Lojiji...
Alàáfià fun yin !
Emi gan-an ni ! Ɛ wo ɔ́wɔ́ mi, ɛ wo ɛsɛ̀ mi !
Oluwa mi ati Ɔlɔrun mi !


Jesu farahàn awɔn ɔmɔ-ɛ̀hin rɛ̀ fun ogojì ɔjɔ́. Ɔkpɔ̀ eniyan ti nwɔn tó nkan bíi ɔgɔ́run marun ni nwɔn rí i lɛ́ɛ̀kannáà. Li ɔjɔ́ kan bi awɔn ɔmɔ-ɛ̀hin méèlókan ti nkpɛja lɔ́wɔ́...
Njɛ́ ɛ rí ɛja mú bi ?
Rárá o ! a kò rí ohunkohun mú.
Ɛ ju àwɔ̀n yin si ɛ̀gbɛ́ keji.
Ɛja ló kpɔ̀ tó báyi !
Oluwa ni !
Olukɔ́ni !
Ɛ wá, Ɛ jɛ́ ki a jɛun !


Peterù, njé iwɔ féràn mi nitòótó bi.
Igbà méèta òtò ni Jesu fi bi Peterù li òrò yi.
Béèni, Oluwa, iwɔ mò kpé mo féràn rɛ.
Bi ó bá rí béè, máa bó awɔn àgùtàn mi.
Máa tèlé mi !
Mo ti gba gbogbo agbára li òrun ati li aiyé. Ɛ lɔ si gbogbo aiyé, ki ɛ si sɔ gbogbo orilè-èdè di ɔmɔ-èhin mi. Ɛ ma tè wɔn bɔmi ní orúkɔ Baba, ati niti Ɔmɔ ati niti Ɛmi Mimɔ. Ɛ ma kó wɔn li ohun gbogbo ti mo ti kó yin.
Ki ɛ mò kpé mo wà kpèlú yin ni gbogbo ɔjó titi fi dé òkpin aiyé.
Bi ó ti sòrò yi tán, a gbé e lɔ sókè òrun. Oun yóò tun kpadàwá bi o ti wí. Lati wá she idájó gbogbo eniyàn...

Jesu wá lɔ, awɔn ɔmɔ-ѐhin rѐ duro ni gbigba àdúrà ni Jerusalɛmu. Nigbànáà ni Ɛmi Mimɔ́ wá bà lé wɔn. Ɛmi Ɔlɔrun ti ó ngbé inu Jesu wá ngbé inú awɔn ɔmɔ-ѐhin rѐ nisisiyi kpѐlú. O wá sɔ wɔn di awɔn eniyàn titun, awɔn ɛlɛ́ri Jesu Kristi.










Nibigbogbo lóri ilѐ ayé ni gbogbo awɔn ti ntѐlé Jesu ma nkpéjɔ lati gbàdúrà ati lati ka Bibeli. Nwɔn a máa bu búrɛ́di, nwɔn a si máa kpin ago wáinì lati fi she iránti iku Jesu. Nwɔn nshe aláàbákpin ifɛ́ ti Ɔlɔrun fi si wɔn lɔ́kàn.


Ilékpa Ɔlɔrun fun eniyàn wá rí imúshɛ rɛ̀ nikpasɛ̀ Jesu.
Jesu fɛ́ràn rɛ. Máa dúkpɛ́ lɔ́wɔ́ rɛ̀, ki o si máa sìn in.
Ɔlɔrun fɛ́ aráyé tóbɛ́ɛ̀ ti ó fi ɔmɔ bíbí rɛ̀ kanshosho fúnni. Ɛnikɛ́ni ti ó bá gbà á gbɔ́ ti bɔ́ lɔ́wɔ́ ikparun, oun si ní ìyè àìnikpɛ̀kun.
WILLEM DE VINK

# ITAN JESU KÒ KPARÍ

Awɔn ɛlɛ́rí mɛ́rin ɔ̀tɔ̀ɔ̀tɔ̀ ni ìgbà aiye Jesu ni nwɔn dá iwe kɔ̀ɔ̀kan kɔ lóri rɛ̀. Awɔn iwé Ihinrere wɔnyi ni a kójɔkpɔ̀ ninu Bibeli. Iwɔ náà lè kà á !

MATTEU
Matteu jɛ́ ɔkan ninu awɔn ɔmɔ-ɛ̀hin mejilá nì. Jesu kpè é. O si she bi ó ti jóòkó lɛ̀hin ibi ishɛ́ agbowó-orí tó nshe ni Kapánáúmù ni Jesu kpè é. O wá ya awɔn eniyàn lɛ́nu wikpé Jesu yan agbowó-orí li ɔmɔ-ɛ̀hin. Kpukpɔ̀ ninu itàn ti Matteu kɔ ni o shɛlɛ̀ loju oun alara gan-an.

MARKU
Marku kɔ ihìnrere kúkúrú kan (Ihinrere jɛ́ iròhin ayɔ̀ gɛ́gɛ́bi o ti tumɔ̀si gan-an). Jesu tun wà li ɔmɔdé nigbati ó ngbé ni ilɛ̀ Israeli. Marku máa saba nlɔ lɔdɔ Peteru lɔ́kpɔ̀ igbà. Peteru yi tilɛ̀ kpè é ni "ɔmɔ mi" ninu iwé rɛ̀ kan. Láikpɛ́, Marku ati Pɔ́ɔlù wá di aláàbáshishɛ́kpɔ̀.
Pɔ́ɔlu li ɛniti ó mú ɔ̀rɔ̀ Jesu dé ilú òyinbó.

LUKU
Biótilɛ̀jɛ́ wikpé Luku kò jɛ́ ɔkan ninu awɔn ɔmɔ-ɛ̀hin, sibɛ̀ oun náà kɔ ihinrere kan. Onishègùn ara Griki li oun jɛ́. Ki ó tó dikpé ó kó itàn rɛ̀ jɔ, Luku ti kpàdé ɔ̀kpɔ̀ eniyàn ti nwɔn ti bá Jesu kpàdé. Oun li ó she àkójɔkpɔ̀ awɔn ìrírí awɔn onigbàgbɔ́ àkɔ́kɔ́ nigbati ijɔ fi bɛ̀rɛ̀ ninu iwé "Ishe awɔn Aposteli".

JOHANNU
Nigbàkpúkpɔ̀ ni nwɔn máa nkpe Johannu ni "olùfɛ́" nitoriti ó sunmɔ́ Jesu timɔ́timɔ́. O sholóòtɔ́ sii titi dé oju ikú rɛ̀ lorí àgbélèbú. Ni okpin ihinrere rɛ̀, ohun ti o kɔ niyi : Ɔkpɔ̀lɔ́kpɔ̀ nkan miràn ni Jesu she , shugbɔ́n a kɔ eyi ki ɛ bá le gbàgbɔ́ wikpé Jesu Kristi ni Messáyà náà ti a ti she ilérí nikpa rɛ̀. Nikpa shishe bɛ́ɛ̀, ɛ o tikpasɛ̀ orúkɔ rɛ̀ ni ìyè. Láàárin awɔn ɔmɔ-ɛ̀hin, ó jɔ bi ɛnikpé Johannu li o kpɛ́ jùlɔ ninu ayé. Oun yi kannáà li ɛniti ó kɔ iwé "Ifihàn" ninu eyiti o ròhin ishíkpayá ti o ní lori Jesu ninu ogo.

FUN IWƆ ALARA GAN-AN !
Itàn Jesu kò kparí. Ɔkpɔlɔ́kpɔ eniyan ni nkan ɔ̀kpɔ̀ ɔgɔrun ɔdun sɛ́hin ni ó njɛ́ri nikpa bi oun ti ngbé inu ayé wɔn. Bakannáà ni Jesu fɛ́ wɔ inu ayé tirɛ naa, ó si fɛ́ dúró lɛ́ɛ̀gbɛ́ rɛ nigbàgbogbo, o fɛ́ fi ifɛ́ rɛ̀ yi ɔ ká. Kpɛ̀lú rɛ̀, ohun ti ó bá ti shókùnkùn ni máa ndi imɔ́lɛ̀. Ibɛ̀rù ikú kòsi mɔ́, nitoriti ó nfún wa ni ireti iyè ainikpɛ̀kun. Nikpasɛ̀ Jesu, ètò Ɔlɔrun fun ayé rɛ le rí imúshɛ. O kú irin-àjò rere kpɛ̀lú rɛ̀ !





# JESU KRISTI

Iwe yi jɛ́ iwé itàn tòótɔ́ nikpa Jesu Messáyà. Ó gbé ni ilɛ̀ Israeli fun nkan bii ɛgbɛ̀rún ɔdun meji sɛ́hin. Olúkúlùkù ɛniti ó bá a kpàde li ó jɛ́ ohun iyàlɛ́nu fún. Kosi ɛnikɛ́ni ti ó ti she ohun ti oun nshe rí. Ɛnikɛ́ni kòi ti wi ohun ti ó nwi. Awɔn ishɛ́ iyanu ma nshɛlɛ̀ nibiti Jesu bá ti wà. Bɛ́ɛ̀ni, ó mú ayɔ̀ ati ire bá awɔn ɛniti ó fɛ́ràn lati gbɔ́ tirɛ̀. A kpa á latɔwɔ́ awɔn ɔ̀tá rɛ̀. Sibɛ̀, itàn náà kòi ti kpari. O tun ntɛ̀siwáju di òni. Farabalɛ̀ kà á funra rɛ ki o bá le gbɔ́ awɔn àlàyé lóri ishɛ́-iránshɛ́ Jesu ti a kɔ nibámu kpɛ̀lú awɔn Iwe Ihinrere mɛ́ɛ̀rin kan.

langue: Yoruba